# IJỌ́ ÒRÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́-ÌYANU

Olú Ilé-Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà

**ÀDÚRÀ SÓRÍ IYẸ̀PẸ̀ (APÁ KẸ́RIN)**

1. Mo gbé ìyẹ̀pẹ̀ yìí dání gẹ́gẹ́ bí ti Mósè, mo sì lò ó gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbápàdé fún ilẹ̀ tí mo ti bù ú. Jẹ́ kí ohungbogbo tó mbẹ nínú ìyẹ̀pẹ̀ yìí di ẹyin-iná láti yangbẹ irúgbìn òkùnkùn ìyówù ní agbègbè mi, ní orúkọ Jésù.
2. Jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ yìí gbé ìdájọ́ padà sí àgọ́ òkùnkùn tó lòdì ìyówù lórí ilẹ̀ agbègbè mi, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa, sọ agbègbè mi di nlá kọjá èròngbà mi, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tó n pọ́n agbègbè mi lójú, túká, ní orúkọ Jésù.
5. Ìmọ́lẹ̀ ògo Ọlọ́run, tàn sí àyíká mi láti di iná ajónirun, kí ó sì run gbogbo ìfarahàn òkùnkùn ní agbègbè mi, ní orúkọ Jésù.
6. Mo parun gbogbo ohun-ìní ibi àti iṣẹ́ ẹ̀mí òkùnkùn nínú ilé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Wò ó bí ẹni tó gbe ìyẹ̀pẹ̀ s'ọ́wọ́ nípa igbàgbọ́ báyìí, kí o sì bẹ̀rẹ̀ siní wí pé, "Mo wọ́n erùpẹ̀ lòdì sí ìwọ ìránṣẹ́ òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
8. Mo yàlárọ gbogbo ẹsẹ̀ búburú tó n rìnkiri nítorí mi, ní orúkọ Jésù.
9. Jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ tí mo dà yìí sọ ibùgbé mi di ibi tí kò ṣeé gbé fún àwọn jẹranjẹran àti àwọn mùjẹ̀mùjẹ̀. Jẹ́ kí erùpẹ̀ yìí rin ìrìn-àjò lábẹ́ àrá agbára Rẹ, kí o sì parún gbogbo òjíṣẹ́ àti ikọ̀ òkùnkùn tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
10. Nípa ìyẹ̀pẹ̀ yìí, mo sọ gbogbo ògèdè àti gbólóhùn sàtánì tí wọ́n ṣe l'ágbégbè mi di aláìlágbára, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, jẹ́ kí ilẹ̀ tó mbẹ ní abẹ́ àtẹ́lẹsẹ̀ mi di ẹ̀rí isèso Rẹ, ní orúkọ Jésù.

12. Olúwa, jẹ́ kí àyíká mi fa àwọn ènìyàn tí yóò mú àláfíà, ọgbọ́n àti àjọṣepọ̀ tó lérè wá, ní orúkọ Jésù.
13. Bàbá, jẹ́ kí àwọn ibùkún ọ̀run rọ̀ bí òjò sí agbègbè mì, ní orúkọ Jésù.
14. Ẹ̀mí Mímọ́, ṣàbalé, kí O gba ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iṣàkóso agbègbè mi, ní orúkọ Jésù.